# Àgbéyẹ̀wò Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Àtijọ́ Nínú Eré Ọ̀yọ̀ Ní Ikún Àkókó

**Deborah Bámidélé Arówóṣẹgbẹ́, *Ph.D.***
*Department of Linguistics and Languages,*
*Adékúnlé Ajáṣin University, Àkùngbá-Àkókó*
*dbamidelearowosegbe@gmail.com*

## *Àṣamọ̀*

*Púpọ̀ nínú àwọn ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà bá ara wọn sọ̀rọ̀ láìlo ọ̀rọ̀ ẹnu ló ti ń lọ sókun ìgbàgbé; bí a kò bá sì tètè máa ṣe akọsílẹ̀ àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ náà, ó ṣe é ṣe kí wọ́n di àfìsẹ́yìn tí eégún ń fiṣọ. Èyí ni ó mú kí á ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ọ̀nà wọ̀nyí bí wọ́n tí súyọ nínú eré Ọ̀yọ̀ ní Ikún Àkókó. Ìlànà ìṣẹ̀tọ́fábo àti ìlànà ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò ni a fi ṣe àtẹ̀gùn iṣẹ́ náà. Ìlànà ìṣẹ̀tọ́fábo dúró lórí àṣà àti ìṣe adúláwọ̀: ó jẹ mọ́ ọ̀nà láti ṣàwárí ẹ̀tọ́ obìnrin láwùjọ kí wọ́n sì fi ẹ̀tọ́ wọn lé wọn lọ́wọ́ nígbà tí tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò fúnka mọ́ àṣà àwùjọ. Ìlànà ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò tí a lò fi hàn pé ipò tí àwùjọ tí irúfẹ́ eré yìí ti ń wáyé fi bíbí àkọ́bí ọmọ lókùú sí ló mú kí wọ́n máa yọ ayọ̀ ńlá bí obìnrin bá fí àkọ́bí ọmọ rẹ̀ bí ààyè ọmọ: wọn a sì máa lo oríṣiríṣi ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ láti kéde dídé ọmọ náà fún àwọn ènìyàn àwùjọ. Ìlànà ìṣẹ̀tọ́fábo tí a lò fi hàn pé ojú kan náà tí àwùjọ fi wo obìnrin tí ó bí àkọ́bí ọmọ rẹ̀ lókùú náà ni obìnrin fi wo irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀; a lérò pé kò yẹ kí a di ẹ̀bi bíbí àkọ́bí ọmọ lókùú lé ìyá ọmọ náà lórí. Yàtọ̀ sí èyí, a ṣe àkíyèsí pé àwọn ènìyàn àwùjọ tí wọ́n bá wà nítòsí àwọn tí ó lo àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí a ṣe àfihàn wọn nínú iṣẹ́ yìí nìkan ló lè gbọ́ àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ náà ní àgbọ́yé, nítorí náà, a dábàá pé kí àwọn ènìyàn àwùjọ yìí máa ṣe àmúlò ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ní àfikún sí ti àtijọ́ wọ̀nyí kí ohun tí wọ́n ń sọ lè yé ọ̀pọ̀ ènìyàn.*

**Kókó Ọ̀rọ̀:** Ọ̀yọ̀, Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀, Àkọ́bí Ọmọ, Bíbí Òkú Ọmọ, àíkàragbá

## Ìfáárà

Kí àgbàdó tó dé ayé, ohun kan ni adìyẹ ń jẹ. Kí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé tó dé àwùjọ Yorùbá ni Yorùbá ti ní oríṣiríṣi ọ̀nà tí wọ́n ń gbà bá ara wọn sọ̀rọ̀ yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀ ẹnu. Lára àwọn ọ̀nà náà ni lílu agogo bí àpẹẹrẹ; alágogo ọba lè lu agogo káàkiri ìlú láti kéde iṣẹ́kíṣẹ́ tí ìlú ní fún àwùjọ, a lè lo ìwo erin láti pe àjọ bí ọba bá fẹ́ rí àwọn ènìyàn ìlú, àwọn asunrárà a máa fi ọ̀rọ̀ tó ń lọ tó èrò àwùjọ létí. Bákan náà, àwọn òpìtàn, ọba, ìjòyè, ẹlẹ́gbẹ́jẹgbẹ́ ni wọ́n ní ọ̀nà tí wọn ń gbà fi èrò wọn hàn ní àwùjọ kan. Àkíyèsí wa ni pé lónìí, àwọn ọ̀nà tí a ń gbà bá ara sọ̀rọ̀ ní àwùjọ Yorùbá tí ń yàtọ̀ sí ti àtijọ́. Ìlò rédíò, tẹlifíṣàn, kọ̀ǹpútà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ló wọ́pọ̀ ní àwùjọ lónìí, síbẹ̀, a kò ṣàìrí àwọn ibi tí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àtijọ ti wúlò. Nínú àpilẹ̀kọ yìí, a yẹ eré *Ọ̀yọ̀* ní Ikún Àkókó wò léte àtiwo àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tó súyọ níbẹ̀ àti ìtumọ̀ tí irúfẹ́ àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ ní sí àwọn òsùnsùn afọ̀. Eré tí àwọn ènìyàn ìlú Ikún Àkókó ń ṣe láti fi ayọ̀ wọn hàn pé ọmọ wọn fi àkọ́ní oyún bí àlàyè ọmọ ni wọ́n ń pè ní eré *Ọ̀yọ̀*.

## Tíọ́rì Àmúlò

Tíọ́rì ìṣẹ̀tọ́fábo àti tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò ni a fi ṣe àtẹ̀gùn iṣẹ́ yìí.

## Tíọ́rì Ìṣẹ̀tọ́fábo

Orí àṣà àti ìṣe àwùjọ adúláwọ̀ ni a gbé tíọ́rì yìí lé. Kọ́láwọlé (1997:24) ṣàlàyé ohun tí ìṣẹ̀tọ́fábo jẹ́ nígbà tí ó sọ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì pé ìṣẹ̀tọ́fábo ni:

> … the totality of feminine self-expression, self-retrieval and self-assertion in positive cultural ways.
>
> … àpapọ̀ ohun tó níí ṣe pẹ̀lú obìnrin ní ti ìfi-èrò-inú-ẹni-hàn, ìgba-ẹ̀tọ́-ẹni-padà àti ìfèrò-ọkàn-ẹni-hàn lọ́nà tí yóò ṣàfihàn wọn dáradára nínú àṣà.

Àṣà adúláwọ̀ kó ipa pàtàkì lórí ìgbé-ayé obìnrin adúláwọ̀. Ṣíṣe aya àti ìyá ṣe pàtàkì sí obìnrin adúláwọ̀: ọ̀rọ̀ ọmọ, ọ̀rọ̀ àjùmọ̀-tọ́-ọmọ àti ìbára-ẹni-tan jẹ wọ́n lógún. Àwọn obìnrin adúláwọ̀ gbàgbọ́ pé ipò ìdílé ṣe pàtàkì: wọ́n rí ìdílé bí òpó pàtàkì tí ìdàgbàsókè àwùjọ gùn lé, wọn kò rí i bí ọ̀kan lára ọ̀nà ìjẹgàba ọkùnrin lórí obìnrin. Ìgbàgbọ́ àwọn agbátẹrù ìlànà yìí ni pé àwùjọ ń fi àwọn ẹ̀tọ́ kan du obìnrin nípasẹ̀ àṣà; ìlànà yìí sì ń rọ àwọn obìnrin láti jà fún ẹ̀tọ́ wọn. Adébọ̀wálé (2005:34) fi ẹsẹ̀ èrò yìí múlẹ̀ nígbà tí ó ṣàlàyé ní èdè Gẹ̀ẹ́sì pé ìṣẹ̀tọ́fábo:

> urges women not to accept the constraints imposed on them by culture, and encourages them to fight for their rights in a way that will make meaningful progress and advancement possible for them.
>
> rọ àwọn obìnrin kí wọ́n máṣe tẹ́wọ́gba agbára tí àṣà lò lé wọn lórí: ó gbà wọ́n nímọ̀ràn láti jà fún ẹ̀tọ́ wọn lọ́nà tí yóò fi mú ìlọsíwájú àti ìgbéga tó nítumọ̀ bá wọn.

Ọ̀kan lára ọ̀nà tí a lè gbà ṣe èyí ni kí a wo ohun tí obìnrin ń gbé ṣe ní àwùjọ. Ìlànà ìṣẹ̀tọ́fábo ń ṣe ìtanijí láti tú àṣírí ìrẹ́nijẹ tí àṣà adúláwọ̀ gbé lé obìnrin lórí tó sì ń dènà òmìnira wọn láti jà fún ẹ̀tọ́ wọn àti kí àwùjọ le fi ẹ̀tọ́ tó tọ́ si obinrin fún un láwùjọ.

**Tíọ́rì Ìfojú-Àṣà-Ìbílẹ̀-Wò**

Tíọ́rì mìíràn tí a tún lò ni tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò. Àṣà àwùjọ ni ìlànà yìí fúnka mọ́. Àṣà ní í ṣe pẹ̀lú ohunkóhun tó bá jẹ mọ́ èdè, ìgbàgbọ́, ẹ̀sìn, ìhùwàsí àti ìṣe àwọn ẹ̀yà kan. Àwọn agbátẹrù tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò gbàgbọ́ pé iṣẹ́ tí lítíréṣọ̀ máa ń ṣe ni láti dáàbò bo àṣà àti ìṣẹ̀ṣe àwùjọ (Bennet, 1979:10). Adéwọyè (1988:2) sọ pé lítíréṣọ̀ (yálà lítíréṣọ̀ alohùn tábí lítíréṣọ̀ àpilẹ̀kọ) jẹ́ jíńgí tí ó ṣe àfihàn àṣà àti ìṣe àwọn ẹ̀dá tó ni irúfẹ́ àṣà bẹ́ẹ̀.
Kò sí bí a ṣe lè yọ ọwọ́ kílàńkó àṣà kúrò nínú lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ṣáájú àkókò yìí ni Abímbọ́lá (1977:13) ti sọ pé ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò ni ó yẹ ká fi ṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá nígbà tí ó sọ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì pé:

> The cultural approach must be adopted for the analysis of Yorùbá literature. Literature is culture and no literature can be meaningfully analyzed outside the facts of the culture which produced it.
>
> Ìlànà ìfojú-àṣà-ìbílẹ-wò ni a gbọ́dọ̀ mú lò fún ṣíṣe ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ Yorùbá. Àṣà ni lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀ ni kò sí ìtúpalẹ̀ lítíréṣọ̀ tí a lè ṣe kó múná dóko láìwò ó mọ́ àṣà tó bí irúfẹ́ lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀.

Nígbà tí ó ń ṣàlàyé lórí tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀ wò, Adéyẹmí (2001:155) fi yéni pé ẹni tí yóò bá lo tíọ́rì yìí fún iṣẹ́ lámèyítọ́ gbọ́dọ̀ ní ìmọ̀ kíkún nípa àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá.
Ohun tí a gbàgbọ́ ni pé àṣà kò dúró lójú kan; ó máa ń bá ìgbà yí ni. Atáyéṣe ni àṣà. A lè ṣe àmúlò àṣà àtọ̀húnrìnwá lọ́nà tí kò fi níí pa àṣà tiwa tó wuyì lára.

Níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé orí àṣà àti ìṣe àwùjọ adúláwọ̀ ni a gbé ìlànà ìṣẹ̀tọ́fábo lé, tí ọ̀rọ̀ ṣíṣe aya àti ìyá sì ṣe pàtàkì sí obìnrin adúláwọ̀, tí eré *Ọ̀yọ̀* tí a fẹ́ yẹ̀ wò sì níí ṣe pẹ̀lú obìnrin àti ọmọ, a lérò pé tíọ́rì ìṣẹ̀tọ́fábo yóò wúlò láti ṣe ìtúpalẹ̀ àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ nínú eré *Ọ̀yọ̀*. Èyí ni yóò sì ràn wá lọ́wọ́ láti mọ ojú tí obìnrin fi wo ara rẹ̀ nípasẹ̀ àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ náà. Bákan náà, a lérò pé tíọ́rì ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò yóò wúlò láti wo àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí ó jẹ yọ nínú eré *Ọ̀yọ̀* tí ó jẹ́ abala kan nínú lítíréṣọ̀ ilẹ̀ Yorùbá; èyí yóò sì jẹ́ kí a mọ àrokò tí a fi wọ́n pa ránṣẹ́ sí àwùjọ tí eré náà ti ń wáyé.

## Èrò Àwọn Onímọ̀ Lórí Àwọn Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Àtijọ́

Ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ bí i: Badà (1973), Owólabí, Adéràntí, Olúnládé, àti Ọlábímtán (1985), Ọ̀pádọ̀tun (1986), Mustapha, Oyèrìndé, Àlàgbé, àti Adébọ̀wálé (2009) àti Fáyẹmí (2013), ni wọ́n ti ṣíṣẹ́ lórí oríṣirísi ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀ ẹnu ní àwùjọ Yorùbá. Badà (1973) rí àrokò tí ó pè ní àrokò òwe, bí ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà bá ara wọn sọ̀rọ̀ láti òkèèrè wá nípa fífi nǹkan ránṣẹ́ sí ara wọn tí wọn yóò sì mọ ohun tí wọ́n bá ara wọn sọ. Owólabí a.y. (1985:95-99) ṣàlàyé pé Yorùbá máa ń lo dídún ìlù, agogo, ìwo fífọn àti fèrè fífọn gẹ́gẹ́ bí àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀; wọ́n ṣàlàyé pé a máa ń fi àwọn nǹkan wọ̀nyí kí ènìyàn, a fi ń kọrin, a fi ń pòwe, a sì fi ń bú ni. Ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sí ẹ̀yà ara tí Yorùbá kò lè fi bá ara wọn sọ̀rọ̀. Yàtọ̀ sí lílo ẹ̀yà ara, gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀, Yorùbá tún máa ń lo ààlè láti sọ pé kí ẹnikẹ́ni máṣe dé ìdí nǹkan tí a pa ààlè lé náà. Oríṣirísi nǹkan ni a lè fi pa ààlè; ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn ló ní ìtùmọ̀ tirẹ̀. Lára àwọn ohun tí a lè lò gẹ́gẹ́ bí ààlè ni igi, yẹ̀pẹ̀, ṣùkù àgbàdo, bàtà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ (Owólabí a.y. 1985:

109). Mustapha A.Y. (2009:17-25) náà rí àrokò gẹ́gẹ́ bí ohun tí àwọn baba wa ń lò gẹ́gẹ́ bí lẹ́tà láti bá ara wọn sọ̀rọ̀ láìlo ọ̀rọ̀ ẹnu rárá. Wọ́n ṣe àlàyé lórí oríṣiríṣi àrokò tí ó wà àti àwọn ẹgbẹ́ tí wọ́n ń lò wọn bí àpẹẹrẹ; babaláwo lè fi ìbò ránṣẹ́ sí ẹlẹ́gbẹ́ rẹ̀ kan láti sọ fún un pé kí ó máa bọ̀ kíákíá. Ó ṣàlàyé pé àròkò pípa jẹ́ ọ̀nà tí a ń gbà gbé ìwà ọmọlúwàbí ró láwùjọ wa, ó ń dín àsìkò fífi ṣòfò kù, kò fi àyè gba ìwà ọ̀daràn tàbí ìwà arúfin láwùjọ Yorùbá. Mustapha a.y. (2009:17-25) gbàgbọ́ pé àìkọ-ibi-ara sí àwọn nǹkan wọ̀nyí mọ́ ń ṣe àkóbá púpọ̀ fún ìwà ìkóra-ẹni-ní-ìjánu àti ìwà ọmọlúwàbí lóde-òní.

Fáyẹmí (2013:71) gbàgbọ́ pé ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àtijọ́ ṣe pàtàkì; nínú àlàyé rẹ̀, ó tọ́ka sí èrò Wilson Des (1987:88) níbi tí ó ti fi pàtàkì ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àtijọ́ hàn nígbà tí ó sọ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì pé:

> …although the traditional media may be old and different, in their principles, from the new systems introduced from abroad, they remain what essentially sustain the information needs of the rural which represent 70% of the national populations of most Third World states.
>
> Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àbáláyé yìí ti pẹ́ tí ìlànà wọn sì yàtọ̀ sí ti ìgbàlódé, síbẹ, àwọn ni wọ́n ń fi ẹsẹ̀ irúfẹ́ ìròyìn tí àwọn tó wà ní ìletò nílò láti gbọ́ múlẹ̀, àwọn ènìyàn wọ̀nyí sì kó ìdá àádọ́rin nínú ọgọ́rùn-ún àwọn ènìyàn tó wà ní ọ̀pọ̀ orílẹ-èdè tó ṣẹ̀ṣẹ̀ ń dìde nílẹ̀.

Ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àtijọ́ kò ṣàiní àléébù tirẹ̀, bí a bá lo ọ̀nà yìí ohun tí a ń sọ lè máà yé àwọn tí àṣà tiwọn bá yàtọ̀ sí ti àwùjọ tí a ti lò ó nítorí pé àṣà àti àwùjọ kan ni irúfẹ́ ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀

kọ̀ọ̀kan jẹ mọ́. Bákan náà ni ó jẹ́ òtítọ́ pé àwọn òsùnsùn afọ̀ irúfẹ́ ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ bẹ́ẹ̀ lè kéré níye; èyí ni ó mú Fáyẹmí (2013:76) dábàá pé kí á walẹ̀ jìn lórí àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àtijọ́ wọ̀nyí kí á lè ṣe àmúlò wọn pẹ̀lú ti ìgbàlódé láti ṣe ìgbéláruge fún ìgbọ́ra-ẹni-yé láàrin oríṣiríṣi ẹ̀yà ní ilẹ̀ adúláwọ̀. Àfàyọ tí a ṣe nínú iṣẹ́ àwọn onímọ̀ wọ̀nyí ni pé a kò fẹ́ oríṣiríṣi ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí ó jẹ mọ́ àṣà àti ìṣe àwùjọ̀ kọ̀ọ̀kan kù ní ilẹ̀ àdúláwọ̀ pàápàá ilẹ̀ Yorùbá bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ti wà ní àwùjọ bákan náà. A ṣe àkíyèsí pé ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sí òǹkọ̀wé tí a mọ̀ tí ó ṣiṣẹ́ lórí bí ìlò àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ wọ̀nyí ti jẹ yọ nínú àwọn eré ìbílẹ̀ Yorùbá. Èyí ni ó mú kí a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àtijọ tó súyọ nínú eré *Ọ̀yọ̀* tí í ṣe ọ̀kan lára eré ìbílẹ̀ Yorùbá.

## Eré *Ọ̀yọ̀*

Ẹ̀bùn pàtàkì ni ọmọ jẹ́. Bí obìnrin bá wọ ilé-ọkọ tí ó ń tó oṣù mẹ́ta sí mẹ́fà tàbí ọdún kan tí kò gbọ́ pá, tí kò gbọ́ po, ọkàn àwọn èniyàn ọkọ àti ti aya pàápàá kò ní balẹ̀. Oríṣiríṣi aájò ni wọn yóò máa ṣe láti lè jẹ́ kí wọ́n rí ọmọ bí. Ládélé, Mustapha, Aworìndé, Oyèrìndé àti Ọládàpọ̀, (2006:138) fìdí aájò ọmọ ṣíṣe yìí múlẹ̀ nígbà tí wọ́n sọ̀rọ̀ nípa tọkọ-taya tí kò tètè rọ́mọ bí pé:

> Bí wọ́n ti ń wọ ilé babaláwo ni wọn yóò máa wọ ilé oníṣègùn. Bí ìyàwó ti ń jẹ jíjẹ ni yóò máa mu mímu. Bí ọkọ ti ń náwó ni yóò máa nára.

Bí ọmọbìnrin bá wọlé ọkọ tí Ọlọ́run yọ̀nda ọmọ fún un, yálà láìṣe aájò tàbí lẹ́yìn ọ̀pọ̀ aájò, ayọ̀ òbí, pàápàá, ìyá ìyàwó lórí irúfẹ́ ọmọ bẹ́ẹ̀ kò níí lópin. Bí wọ́n ṣe ń sáré síwá ni wọn yóò máa sáré sẹ́yìn, bí wọ́n ti ń yọ̀ sọ́tùn-ún ni wọn yóò máa yọ̀ sósì.

Ìwádìí fi hàn pé bí inú àwọn ènìyàn wọ̀nyí ti dùn tó tí wọn kò sì lè ṣe gbogbo ohun tí wọ́n ti lérí pé àwọn yóò ṣe bí ayọ̀ náà bá lè tẹ̀ wọ́n lọ́wọ́ ló fa ìpèdè àwọn ènìyàn àwùjọ yìí pé *ọ̀yọ̀ lẹ* èyí ni pé ayọ̀ lójo tàbí ayọ̀ kò lágbára. Ayọ̀ tí wọ́n ń yọ̀ yìí ni wọ́n ń pè ní *Ọ̀yọ̀* ní àwọn agbègbè tí irúfẹ́ ayọ̀ bẹ́ẹ̀ ti ń wáyé. Eré tí àwọn obìnrin sì ń ṣe láti fi ayọ̀ wọn hàn ni wọ́n ń pè ní *eré Ọ̀yọ̀*. Eré yìí kò ní oṣù kan pàtó tí wọ́n ń ṣe é láàrin ọdún; àkókò tí obìnrin kan bá bí àkọ́bí ọmọ ní alàáyè ni ó máa ń wáyé. Ohun tí a ṣe àkíyèsí ni pé ó fẹ́rẹ̀ẹ́ jẹ́ pé ìyá tí ọmọbìnrin rẹ̀ bímọ ni ó máa ń ní ìmọ̀lára ayọ̀ ọmọ jù lọ; òun ni ó ní àǹfàání láti ya ọjọ́ kan sọ́tọ̀ tí gbogbo obìnrin àdúgbò rẹ̀ yóò bá a ṣeré *Ọ̀yọ̀* ya ojúlé mọ̀lẹ́bí, ará àti ọ̀rẹ́ gbogbo; àwọn ènìyàn a sì máa fún un ní ẹ̀bùn owó.

Ní gbogbo àkókò tí àwọn obìnrin bá ń ṣe eré yìí, yálà ní kété lẹ́yìn ìbímọ tàbí ọjọ tí a yà sọ́tọ̀ fún irúfẹ́ eré bẹ́ẹ̀, kò sí ìlù lílù rárá, ọ̀wọ́ ṣẹ̀kẹ̀rẹ̀ àti àtẹ́wọ́ ni àwọn obìnrin ń lò. Bàbá ìkókó nìkan ló ní àǹfàání láti lu ìlù láti kéde dídé àkọ́bí ọmọ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí a ó ti fi hàn níwájú. Ìwádìí fi hàn pé ọ̀pọ̀ ìlú bí Ikún, Ìfira, Ìpèsì, Ìṣùà, Ìkákùmọ̀ àti Ìbòròpa ní agbègbè Àkókó ni eré náà ti fẹsẹ̀ múlẹ̀ jù lọ; irúfẹ́ eré yìí tún maa ń wáyé ní Ìdógún àti Ìdóàní ní ìjọba ìbílẹ̀ Ọ̀sẹ́ (Olútóyè, 1982:9) ṣùgbọ́n àlàyé wa níhìn-ín yóò dá lórí Ikún Àkókó. Orí àkọ́bí ọmọ nìkan ni *eré Ọ̀yọ̀* dá lé (yálà ọmọ náà wà láyé tàbí kò sí láyé); bí ọmọ ìkókó náà tilẹ̀ gbẹ́mìí mì ní kété tó dé ayé, níwọ̀n ìgbà tí ó bá ti kígbe kí ẹ̀mí tó bọ́ lára rẹ̀, gbogbo ayọ̀ tí ó bá yẹ ni wọn yóò yọ̀ lé e lórí. Ìwádìí fi hàn pé eré *Ọ̀yọ̀* kì í wáyé nígbà tí ọmọbìnrin tí àwùjọ tàbí mọ̀lẹ́bí bá fura sí pé ó ti ṣẹ́yún rí bá bímọ. Ìgbàgbọ́ àwọn ènìyàn àwùjọ yìí ni pé irúfẹ́ ọmọbìnrin bẹ́ẹ̀ ti ṣẹ́ oyún tí ó yẹ kí ó fi bí àkọ́bí ọmọ

rẹ̀ nítorí náà, ọmọ tí ó bí yìí kì í ṣe àkọ́bí rẹ̀. Àwọn òbí rẹ̀ yóò kàn dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run tí ó jẹ́ kí ọmọ wọn sọ̀ láyọ̀ ni.

Ìwádìí fi hàn pé ipò tí àwujọ yìí fi bíbí àkọ́bí ọmọ lókùú sí ni ó mú kí àwọn obìnrin máa yọ̀ bí wọ́n bá bímọ àkọ́bí tí ọmọ náà sì kígbe nígbà tí wọ́n bí i. Orí burúkú ni àwùjọ yìí ka bíbímọ àkọ́bí lókùú sí. Wọn kò sì lérò pé ó yẹ kí irúfẹ́ ẹni tí a kò bá yọ irúfẹ́ ayọ̀ tí a ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ yìí fún bá ẹnikẹ́ni yọ̀ níwọ̀n ìgbà tí orí tirẹ̀ ti burú gẹ́gẹ́ bí ìpèdè wọn (a ó fi èrò ọkàn wa lórí èrò àwùjọ yìí hàn níwájú). Oríṣiríṣi ọ̀nà ni àwọn ènìyàn àwùjọ níbi tí eré *Ọ̀yọ̀* ti ń wáyé gbà ń sọ fún ara wọn pé àwọn bí àkọ́bí ọmọ yálà ó yè tàbí ó kú.

**Òríṣiríṣi ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí ó hànde nínú eré *Ọ̀yọ̀***

Bí obìnrin kan bá fi àkọ́bí rẹ̀ bí ààyè ọmọ, ẹbí ọkọ àti taya máa ń lo àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ bí; ìró ìbọn, dídún ẹnu, dídún àíkàragbá, ìlò ewé, àti ìró ìlù láti kéde dídé ọmọ náà. Bákan náà, bí ó bá jẹ́ òkú ọmọ ni obìnrin fi ọmọ náà bí, àwùjọ a máa pa òṣé láti tọ́ká sí irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀. A ó ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ wọ̀nyí ní ọ̀kọ̀ọ̀kan.

***Ìró ìbọn gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀:*** Bí Ọlọ́run bá ṣe é tí obìnrin ru oyún àkọ́ní rẹ̀ tí ó sọ̀ láyọ̀, tí a gbóhùn ìyá tí a gbọ́ ti ọmọ, bàbá ìkókó yìí yóò yìnbọn láti fi kéde dídé àlejò tí wọ́n ti ń fi oṣù mẹ́sàn-án tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ múra dè. Dípò tí ìbá fi máa yalé kọ̀ọ̀kan láti sọ fún àwọn ẹbí àti ará pé ìyàwó òun bímọ, ìbọn ni yóò yìn láti ṣe ìkéde yìí. Bí bàbá ìkókó kò bá sí nítòsí ní àkókò tí a bí ọmọ náà tàbí tí ó jẹ́ ẹni tí ó ń bẹ̀rù láti yìnbọn, baba rẹ̀ tàbí ẹnikẹ́ni láàrin ẹbí rẹ̀ lè yin ìbọn yìí láti kéde dídé ọmọ tuntun

náà àti láti fi ayọ̀ wọn lórí dídé ọmọ náà hàn; èyí fi bí Yorùbá ṣe káràmásìkí ọ̀rọ̀ ọmọ sí hàn. A ní láti sọ níhìn-ín pé kì í ṣe àkókò eré *Ọ̀yọ̀* nìkan ni ìbọn yínyìn máa ń wáyé ní àwùjọ yìí: wọn a máa yin ìbọn nígbà tí àgbàlagbà bá kú; láti kéde ìpapòdà irúfẹ́ àgbà bẹ́ẹ̀, wọn a tún máa yìnbọn bí wọ́n bá ń sin òkú àgbà tàbí bí wọ́n bá ń ṣe ayẹyẹ ìsìnkú àgbà. Ohun tí ìbọn ti eré Ọ̀yọ̀ fi yàtọ̀ ni pé ìgbà kan ṣoṣo ni a ní láti yin irúfẹ́ ìbọn bẹ́ẹ̀; yínyin ìbọn lásìkò ìsìnkú máa ń ju ẹyọ kan lọ; ó dúró lórí bí àwọn ọmọlókùú bá ti ní owó tó láti ṣe ìnàwó ẹ̀tù ìbọn. Yàtọ̀ sí pé àwùjọ Yorùbá máa ń lo ìbọn fún ogun jíjà, ìbọn yínyìn ní àwùjọ Yorùbá lè jẹ́ àmì ìṣẹ́gun, ó lè jẹ́ láti kí ni kú oríire; wọn a máa lò ó láti fi sin olóyè tí a ṣẹ̀ṣẹ̀ fi ewé oyè há létí lọ sí ilé rẹ̀ (Ọlájubù, 1978:107), ó sì tún lè jẹ́ láti fi ìdùnnú hàn, bí àpẹẹrẹ; ayọ̀ pé àwọn ọmọ gbẹ̀yìn arúgbó wọn ní ó fa ìbọn yínyìn ní àkókò ìsìnkú àgbà. Bákan náa ni yínyin ìbọn nínú eré *Ọ̀yọ̀* jẹ́ láti kéde fáyé gbọ́ àti láti fi ìdúnnú hàn pé a bí ọmọ tuntun sáyé; nítorí náà ìlò ìbọn níhìn-ín wà ní ìbámu pẹ̀lú àṣà Yorùbá.

***Dídún ẹnu gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀:*** Ní kété tí obìnrin bá bímọ, àwọn obìnrin ilé ọkọ rẹ̀, pàápàá ìyá ọkọ rẹ̀, yóò sáré jáde, wọn yóò fi ọwọ́ lu ẹnu wọn léraléra, ìró tí a ó gbọ́ ni:

| Ìró | Yorùbá Àjùmọ̀lò |
|---|---|
| *Kú kùú ku u u u kú ùúu* tó túmọ̀ sí | "Ẹ máa bọ̀ o, a bí àkọ́bí ọmọ, ó sì kígbe o" |

Ẹnikẹ́ni tó bá wà nítòsí tó bá gbọ́ ìró ẹnu yìí yóò ti mọ̀ pé a bí àkọ́bí ọmọ nínú ilé tí irúfẹ́ àrokò bẹ́ẹ̀ ti jáde, àti pé ọmọ tí a bí náa kígbe nígbà tí a bí i. Àwọn obìnrin tó wà ní àyíká ibi tí fífi

ọwọ́ lu ẹnu yìí tí wáyé yóò dara pọ̀ mọ́ àwọn tó ń yọ̀ láti bá wọn yọ ayọ̀ ọmọ, eré *Ọ̀yọ̀* yóò sì bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu.

Ohun ìdùnnú, ohun ayọ̀ ni àwùjọ yìí ka dídé ọmọ tuntun sí àárin ẹbí sí pàápàá bí irúfẹ́ ọmọ bẹ́ẹ̀ bá jẹ́ àkọ́bí ọmọ ìbáà jẹ́ ọmọkùnrin tàbí ọmọbìnrin. Bí ìyá obìnrin tó bímọ (ìyá-ìyàwó) bá ti gbọ́ pé ọmọ òun ti bímọ tibi-tire náà ni yóò tún bọ́ síta, tí yóò tún máa fi ọwọ́ lu ẹnu léraléra gẹ́gẹ́ bí ìyá-ọkọ ọmọ rẹ̀ ti ṣe nílé tirẹ̀, láti pe àwọn ènìyàn àdúgbò rẹ̀ kí wọ́n wá bá a yọ ayọ̀ ọmọ: àwọn obìnrin ilé àti ti àdúgbò yóò jẹ́ ìpè rẹ̀; eré *Ọ̀yọ̀* yóò tún bẹ̀rẹ̀ ní pẹrẹu. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ẹnu ni àwọn obìnrin wọ̀nyí fi ọwọ́ lù tí wọn kò sọ ohunkóhun, síbẹ̀, àrokò tí wọ́n fi ìró tí fífi ọwọ́ wọn lu ẹnu gbé jáde pa yé àwọn olùgbọ́ ṣùgbọ́n ó lè máà yé ẹni tí kò wá láti àwùjọ náà.

A kò fẹ́ ìlò ìró ẹnu yìí kù ní àwùjọ Yorùbá pàápàá láàrin àwọn àgbẹ̀; àwọn àgbẹ̀ a máa hu sí ara wọn nínú oko láti mọ ibi tí ẹnikejì wà, láti sọ fún un pé ilé ti yá tàbí láti mú kí ó súnmọ́ ibi tí ẹni tí ó pè é wà nítorí náà ìlò dídún ẹnu níhìn-ín láti kéde dídé ọmọ àti fífi ayọ̀ ẹni hàn wà ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò tí ó rí dídún ẹnu gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára ọ̀nà tí Yorùbá gbà ń sọ̀rọ̀ láìlo ọ̀rọ̀ ẹnu. Ìlànà ìṣẹ̀tọ́fábo tí a lò gbàgbọ́ pé ipò ìyàwó àti ipò ìyá ọmọ jẹ obìnrin adúláwọ̀ lógún bákan náà ni àṣà àdúláwọ̀ fi ọmọ sí ipò pàtàkì; ọwọ́ yẹpẹrẹ kọ́ ni wọ́n fi mú ọ̀rọ̀ ọmọ bíbí. Yorùbá jẹ́ ọkan nínú àwọn tó ka ọmọ kún ẹ̀bùn kan tó ṣe pàtàkì jù lọ nínú ẹbùn tí Ọlọ́run máa ń fún ẹ̀dá. Ládélé A.Y. (2006:138) fi èrò yìí múlẹ̀ nígbà tí wọ́n ṣàlàyé pé bí ìgbéyàwó bá ti ń tó ọdún méjì tí a kò kí tọkọ-taya ní “báríkà” ni ẹbí ìyàwó yóò ti máa gba ọmọ wọn nímọ̀ràn láti wá ẹlòmìíran fẹ́ bẹ́ẹ̀ ni ẹbí ọkọ náà yóò máa sọ fún ọmọ wọn láti wá aya mìíràn nítorí

"ènìyàn kò lè ti àárọ̀ rin àgàn"; ojú ẹ̀gàn àti àbùkù ni àwùjọ Yorùbá fi ń wo àgàn. Èyí ni àwọn obìnrin àwùjọ yìí ṣe máa ń fi gbogbo ara yọ̀ bí ọ̀kan lára wọn bá di ìyá ọmọ tàbí di ìyá ìyá ọmọ; nítorí náà, yíyọ ayọ̀ pé wọ́n bí ọmọ túntun níhìn-ín wà ní ìbámu pẹ̀lú tíọ̀rì méjèèjì tí a lò.

***Dídún àíkàragbá (pàńkàrà) gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀:*** Nígbà mìíràn, ó ṣe é ṣe kí ó má jẹ́ ilé baba ìkókó ni wọn bí ìkókó náà sí; ó lè jẹ́ ilé oníṣègùn, ilé arẹmọ tàbí ilé ìgbẹ̀bí, kí wọ́n tó gbé ọmọ náà wọ ilé baba rẹ̀, ọmọdékùnrin kan láti inú ẹbí bàbá ìkókó, yóò mú *àíkàragbá* (igbá tí ó ti ya) lọ́wọ́ òsì, igi kékeré ní ọwọ́ ọ̀tún, yóò bẹ̀rẹ̀ ní gbàgede ìwájú ilé baba ọmọ, yóò sì máa fi igi náà lu àíkàragbá bí ó ti ń wọnú ilé bàbá ọmọ lọ. Àwọn tí wọ́n ń bọ̀ láti ibi tí wọ́n bímọ sí àti ìkókó tí a gbé pọ̀n yóò dúró ní òde tàbí kí wọ́n wà níbi tí a bí ọmọ sí bí ibẹ̀ kò bá jìnnà sí ilé bàbá ọmọ títí tí ọmọdékùnrin náà yóò fi jáde sóde láti inú ilé bàbá ọmọ tí ó wọ̀ lọ. Dídún àíkàragbá yìí ni ó ń pàrokò dídé àkọ́bí ọmọ tuntun sínú ilé náà. Bí àwọn obìnrin ilé bá ti gbọ́ ìró àíkàragbá yìí ni wọn yóò sáré jáde láti fi ijó àti orin pàdé ìkókó. Bí àwọn obìnrin wọ̀nyí ti ń jade ni àwọn obìnrin ti àdúgbò yóò dara pọ̀ mọ́ wọn tí wọn yóò tún ṣeré bí ti ìgbà tí wọ́n kọ́ gbọ́ pé wọ́n bí ọmọ náà. Lẹ́yìn èyí ni wọn yóò gbé ìkókó wọlé baba rẹ̀. Ọ̀pádọ̀tun (1986:81) ṣàlàyé lórí oríṣiríṣi ọ̀nà tí a ń gbà lo agogo ní àwùjọ Yorùbá.

Ọ̀kan lára àwọn ọ̀nà tí ó mẹ́nu bà ni lílo agogo fún ìkéde; láti kéde ọ̀rọ̀ tí ọba fẹ́ sọ, láti kéde àjọ̀dún kan, láti kéde owó orí sísan, láti fi tó ará ìlú létí bí ọba bá fẹ́ bá wọn sọ̀rọ̀, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Iṣẹ́ tí àwùjọ Yorùbá fi agogo ṣe níhìn-ín ni àwùjọ Ikún fi

*àíkàragbá* ṣe nínú eré *Ọ̀yọ̀* èyí tí í ṣe láti kéde dídé ọmọ tuntun sínú ẹbí kan. A nílati sọ níhìn-ín pé kì í ṣe inú eré *Ọ̀yọ̀* nìkan ní ìlò àfọ̀kù igbá (pàǹkàrà) yìí ti ń wáyé; bí ohun ọ̀sìn wọn bá sọ́nù wọn a máa lò dídún àfọ̀kù igbá láti kéde kiri àdúgbò léte àtimú kí àwọn ènìyàn gbọ́ kí ẹni tí ó bá kófìrí ohun ọ̀sìn bẹ́ẹ̀ tàbí kófìrí ẹni tí ó jí i lè wá sọ tàbí lè tú àṣírí irúfẹ́ olè bẹ́ẹ̀; bí ó bá rí bẹ́ẹ̀, a jẹ́ pé ìlò ààkàragbá láti kéde dídé ọmọ tuntun wà ní ìbámu pẹ̀lú ìlànà ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀ wò tí a ṣe àmúlò rẹ̀ nínú iṣẹ́ yìí.

***Ìlù gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀:*** Abala yìí ni ó tún fi ipa bàbá ìkókó lórí kíkéde dídé ọmọ hàn yàtọ̀ sí ìbọn yínyìn tí ó ti ṣáájú. Ní òwúrọ̀ kùtù (ọjọ́ tí ó bá wu bàbá ìkókó láti ṣe bẹ́ẹ̀), ní nǹkan bí agogo márùn-ún, bàbá ìkókó yóò gbé ìlù bẹ̀ǹbẹ́ gun orí àpáta tí kò jìnnà sílé, bí ó bá ti dé orí àpáta, yóò lu ìlù náà láti pàrokò ránṣẹ́ sí àwùjọ pé òun bí ọmọ àkọ́bí àti pé ọmọ náà kígbe nígbà tí a bí i. Ní òde-òní, ìbẹ̀rẹ̀ àti òpin àdúgbò ni bàbá ìkókó ti ń lu irúfẹ́ ìlù bẹ́ẹ̀ nítorí pé àwùjọ ti ń fẹ̀ sí i. Ìwádìí fi hàn pé bàbá ìkókó lọ sí àwọn ibi tí ó lọ náà léte àtijẹ́ kí àwọn ènìyàn púpọ̀ gbọ́ dídún ìlù náà. Bàbá ìkókó yóò lu ìlù náà ní ìgbà méje tàbí ìgbà mẹ́ta (èyí dúró lórí iye ìgbà tí àṣà bá gbà wọ́n láyè láti lù ú ní àdúgbò kọ̀ọ̀kan). Bí àwọn obìnrin tó wà nílé ti ń gbọ́ ìró ìlù yìí ni wọn yóò máa kóra jọ láti fi ijó àti orin pàdé bàbá ìkókó bí ó ti ń sọ̀kalẹ̀ bọ̀ láti orí àpáta tàbí ìpẹ̀kun àdúgbò tó lọ. Bí bàbá ìkókó bá ti sọ̀ lórí àpáta tàbí tí ó dé láti ìpẹ̀kun àdúgbò ni yóò dá ìlù padà sí ibi tí ó ti gbé e ní ilé olórí àdúgbò.

Ohun tí ó kàn ni kí bàbá ìkókó àti ẹbí rẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí í ná owó fún àwọn obìnrin tí bàbá ìkókó ti fi dídún ìlù pè jọ láti bá a yọ ayọ̀ ọmọ. Ìlù jẹ́ ọ̀kan lára ọ̀nà tí Yorùbá ń gbà bá ara wọn sọ̀rọ̀

láìlo ọ̀rọ̀ ẹnu (Ọ̀pádọ̀tun, 1986:102-107, Owólabí a.y. 1986:95-98). Ládélé a.y. (2006:266) fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìlù bẹ̀ǹbẹ́ kì í ṣe ìlù fàájì nítorí pé a kò lè lu òun nìkan fún fàájì tàbí àṣeyẹ pàtàkì; ó ṣàlàyé pé àwọn ológun ló ń jó o láyé àtijọ́; ó ní ìdí nìyẹn tí ó fi jẹ́ pé bẹ̀ǹbẹ́ ni a sáábà ń lù bí a bá ń lọ sí ojú ogun. A tún ń lu bẹ̀ǹbẹ́ fún Ṣàngó ní agbègbè Ẹ̀gbá; bẹ́ẹ̀ sì ni eégún tí kò bá ní ìlù kan pàtàkì a máa jó bẹ̀ǹbẹ́. Àjàyí (2017) fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ìlù lílù ní àwùjọ Yorùbá kì í ṣe láti dáni lárayá nìkan, ó tún ń ṣe kóríyá fún àwọn jagunjagun lójú ogun nígbà tí ó tọka sí i pé Yorùbá máa ń gbé bẹ̀ǹbẹ́, kàkàkí, fèrè àti dùndún lọ sí ojú ogun láti ṣe kóríyá fún àwọn jagunjagun.

Nínú àlàyé rẹ̀, ó fi hàn pé ìlù bẹ̀ǹbẹ́ ni àwọn ọmọlẹ́yìn Kírísítì àti àwọn Mùsùlùmí máa ń lù láti jèrè ọkàn àwọn ènìyàn sínú agbo wọn. Ìlù yìí ni púpọ̀ ilẹ̀ Yorùbá máa ń lù bí wọ́n bá ń kilẹ̀ òkú tàbí nígbà tí wọ́n bá ń sìnkú àna. Dídún ìlù bẹ̀ǹbẹ́ máa ń lọ sókè ju ti àwọn ìlù yòókù; òwe Yorùbá tí ó sọ pé ó tiẹ̀ fọ́ ni, tàbí ó tiẹ̀ ya ni o, ariwo bẹ̀ǹbẹ́ ní í borí ìlù yòókù fìdí èrò yìí múlẹ̀. Ìwádìí fi hàn pé dídún ìlù yìí ní ó ṣokùnfà kí a máa lò ó láti kéde ìbí àkọ́bí ọmọ ní àwùjọ yìí. A lérò pé gígun orí àpáta lọ lu ìlù yìí yóò mú kí púpọ̀ àwọn ènìyàn àwùjọ gbọ́ dídún ìlù náà pàápàá nígbà tí ó jẹ́ pé àárọ̀ kùtù tí ariwò kò tíì sí ló ń wáyé, bákan náa ni lílọ sí ìpẹ̀kun àdúgbò lọ lùlù yóò mú kí ọ̀pọ̀ ènìyàn ní àdúgbò gbọ́ níwọ̀n bí ó ti jẹ́ pé ibi méjì ni wọ́n ti lù ú; ẹni tí kò gbọ́ ti apá kan yóò gbọ́ ti apá kejì.

***Ìlò ewé gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀:*** Àwọn obìnrin, pàápàá àwọn ọmọdé, a máa já ewé dání bí wọ́n bá ń ṣeré *Ọ̀yọ̀* yàtọ̀ sí ìrùkẹ̀rẹ̀ dúdú tí ìyá ìyàwó yóò mú lọ́wọ́. Ìwádìí fi hàn pé oríṣi ewé méjì

yìí: ewé òkikàn (ìyeyè) àti ewé akòko ni àwọn tó ń ṣe eré yìí máa ń já lọ́wọ́ lásìkò eré ṣùgbọ́n nígbà mìíràn wọn a máa lo ewé *ọ̀gbọ̀dọ̀* tí wọ́n lè tètè rí ní àyíká wọn. Igi kan tó fara pẹ́ igi ìrèké, tí àwọn ọmọdé máa ń jẹ́ bí ìgbà tí wọ́n ń jẹ ìrèké ni a ń pè ní *ọ̀gbọ̀dọ̀*. Irúfẹ́ ewé tí àwọn ènìyàn bá já lọ́wọ́ ni yóò sọ ẹ̀yà ọmọ tí wọ́n bí, ewé òkikàn (ìyeyè) ń pàrokò ọmọbìnrin nígbà tí ewé akòko tàbí ọ̀gbọ̀dọ̀ ń pàrokò ọmọkùnrin. Ọ̀pọ̀ ìgbà ni ó jẹ́ pé ewé tí àwọn ọmọdé bá rí nítòsí (ó lè jẹ́ ewé ṣẹ́kẹ́ṣẹkẹ̀ tàbí ewé mìíràn) ni wọn yóò já dání pààpàá bí ó bá jẹ́ ní kété tí obìnrin bímọ ni wọ́n kó eré jáde. Ewé tí wọ́n já lọ́wọ́ yìí ni ó fi hàn pé eré *Ọ̀yọ̀* ni wọ́n ń ṣe. Ewé ṣẹ́kẹ́ṣẹkẹ̀ ń pàrokò eré alákọ̀ọ́bí: yálà ọmọkùnrin tàbí ọmọbìnrin.

A kò fẹ́ ìlò ewé kù ní àwùjọ Yorùbá; Ọ̀pádọ́tun (1986:9, 14) mẹ́nu ba oríṣiríṣi ewé tí Yorùbá ń lò fún àrokò pípa; gẹ́gẹ́ bí àlàyé rẹ̀, ewé ọgbọ́, ìyeyè àti akòko wà lára ewé tí àwọn ẹgbẹ́ ògbóni fi máa ń wẹ ẹdan, bákan náà ni a ń lo ewé akòko fún oyè jíjẹ kí ìgbà ẹni tó joyè lè tùbà kó tùṣẹ. A ń fi ewé ìyálóde (làpálàpá) sàmì ààlà ilẹ̀. Bí a bá fi ewé làpálàpá mọ́ èèpo igi ọ̀mọ̀ fi pàrokò ránṣẹ́ sí babaláwo tí ó ń wo aláìsàn kan, ohun tí èyí ń tọ́ka sí ni pé kí babaláwo bẹ́ẹ̀ jáwọ́ nínú wíwo aláìsàn bẹ́ẹ̀ nítorí pé ó ti di ẹran àjẹgbé fún àwọn ẹlẹyẹ. Láyẹni (1978:200) fi hàn pé jíjá ewé lọ́wọ́ jẹ́ àmì títúúbá; ó ṣàlàyé pé ewé tí àwọn ènìyàn ìlú Aáwẹ́ já dání nígbà tí Ọ̀yọ́ gbógun tì wọ́n ni ó jẹ́ kí Ọ̀yọ́ dá ìlú náà sí; ewé tí wọ́n já dání náà fi hàn pé wọ́n túúba, ti Baba ni wọ́n ń ṣe. Ó ṣàlàyé síwájú sí i pé ewé ìyeyè ni a máa ń sáábà lò nírúfẹ́ àkókò bẹ́ẹ̀, ṣùgbọ́n tí ó bá di pàjáwìrì ewékéwé ni a lè já dání. Ohun tí a ń gbìyànjú láti sọ níhìn-ín ni pé jíjá ewé dání láti pàrokò bíbí àkọ́bí ọmọ ní àbíyè nínú eré Ọ̀yọ̀ wà ní

ìbámu pẹ̀lú tíọ́rì ìlànà ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀ wò tí ó gbàgbọ́ nínú fífi ewé tàbí jíjá ewé dání pàrokò.

***Ọ̀ṣé pípa gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀:*** Olórí burúkú ni àwùjọ Ikún Àkókó ka obìnrin tí àkọ́bí rẹ̀ kò kígbe nígbà tí ó bí i sí; wọn kì í sì í fẹ́ bá irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀ da ohunkóhun pọ̀. Irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀ tàbí ìyá rẹ̀ ni wọ́n máa ń pòṣé sí bí ọ̀rọ̀ bá da àwọn àti ẹlòmíràn pọ̀ bí kò bá tilẹ̀ jẹ́ àkókò eré *Ọ̀yọ̀*. Bí wọ́n ti ń ṣe eré *Ọ̀yọ̀* fún obìnrin tí ó bímọ àkọ́bí yè ni wọn yóò máa pa òṣé sí obìnrin tó bí àkọ́bí ọmọ rẹ̀ lókùú. Ẹni tí ó bí àkọ́bí ọmọ rẹ̀ lókùú àti ìyá tí ọmọ rẹ̀ bí àkọ́bí ọmọ lókùú, kò ní ẹ̀tọ́ láti ṣe eré *Ọ̀yọ̀* tàbí kí ó wo eré náà; bí wọ́n bá fi ojú gán-án-ní rẹ̀ tàbí bí wọ́n bá jó pàdé rẹ̀ ní àkókò irúfẹ́ eré bẹ́ẹ̀, bí ó kí wọn, òṣé ni wọn yóò fi dá a lóhùn, tí ojú yóò sì ti irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀. Olútóyè (1982:9) ti sọ ṣáájú pé ẹni tí akọ́bí ọmọ rẹ̀ kò bá ké nígbà tí ó bí i kò gbọdọ̀ yọjú sóde lákokò ọdún obídan ní Ìyàyú, Ìdóàní; ẹni tí ó bá jí rí irúfẹ́ àwọn obìnrin bẹ́ẹ̀ níláti padà wọlé lọ sùn kí ó lè jí rí olóríire ènìyàn. Ìdí nìyí tí àwọn obìnrin àwùjọ yìí fi máa ń fara ya bí ẹnikẹ́ni bá pòṣé sí wọn.

Bí ó bá jẹ́ ọmọ kékeré ni wọ́n pòṣé sí, ohun tí yóò sọ ni pé àkọ́bí ìyá òun kígbe, bí ó bá sì jẹ́ àgbà obìnrin ni, yóò fi yé ẹni tí ó pòṣé pé òun kò bí àkọ́bí ọmọ lókùú àti pé irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ lè padà lọ sílé wọn kí ó lọ wádìí ẹni tí ó bá bí àkọ́bí ọmọ lókùú níbẹ̀. Bí ó bá sì jẹ́ pé òótọ́ ni irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀ bí àkọ́bí ọmọ rẹ̀ lókùú, ojú yóò tì í, yóò sì jáwọ́ nínú irúfẹ́ aáwọ̀ bẹ́ẹ̀, bákan náà ni yóò fi ìbànújẹ́ kúrò ní sàkání náà. Ìlò òṣé ní àwùjọ yìí ni láti tàbùkù obìnrin tí ó fi àkọ́bí ọmọ bí òkú ọmọ; àwùjọ yìí tilẹ̀ ká irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀ sí olórí burúkú, ẹni àìjírí, ẹni àìjíkò. Bí a bá

pòṣé sí ẹnikẹ́ni tàbí sí ohun kan ní àwùjọ Yorùbá, ohun tí a ń sọ ni pé ẹni tàbí ohun náà kò wúlò, kò nílárí, a kò fẹ́ ẹ. Yàtọ̀ sí òṣé pípa, a kò fẹ́ ìlò ẹnu láti fi pàrokò kù ní àwùjọ Yorùbá; Owólabí a.y. (1986:108-109) fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé a lè lo ẹnu láti sọ̀rọ̀ láìṣí i rárá; yíyọ ṣùtì ẹnu sí ènìyàn pàrokò fífi irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ ṣe yẹ̀yẹ́, bí a bá bèèrè ènìyàn tí a yẹ ẹnu sí ẹ̀gbẹ́ kan júwe ibi tí olúwarẹ̀ wà, ọ̀rọ̀ ìjà ni; nítorí náà lílo òṣé láti parokò orí burúkú nínú eré Ọ̀yọ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lú tíọ̀rì ìfojú-àṣà ìbílẹ̀ wò.

A kò lérò pé irúfẹ́ èrò obìnrin nípa obìnrin ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ yìí tọ̀nà; kò sí obìnrin tí ó wù láti bí òkú ọmọ; kò yẹ kó jẹ́ obìnrin ni yóò máa fi obìnrin ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ ṣẹ̀sín nítorí pé irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀ bí òkú ọmọ. Èrò àwùjọ ni obìnrin gbé lárugẹ níhìn-ín, èyí kò sì dára tó. Ìpayà kí aboyún máṣe bí òkú ọmọ nítorí ojú tí àwùjọ fi ń wo irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀ gan-an lè ṣokùnfà àìsàn tí yóò mú kí irúfẹ́ aboyún bẹ́ẹ̀ bí òkú ọmọ tí ó ń gbìyànjú láti yẹra fún. Ìlànà ìṣẹ̀tọ́fábo kò lè fara mọ́ kí obìnrin máa fi obìnrin ẹgbẹ́ rẹ̀ tó bí òkú ọmọ ṣẹ̀sín; kò yẹ kí bíbímọ lókùú jẹ́ ẹ̀bi irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀ tàbí ti ìyá rẹ̀.

## Àgbálọgbábọ̀

A ti fi hàn nínú iṣẹ́ yìí oríṣiríṣi ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ tí àwọn ènìyàn àwùjọ Ikún ń lò láti kéde dídé àkọ́bí ọmọ sí àwùjọ wọn yálà wọ́n bí ọmọ náà ní alàáyè tàbí wọ́n bí i ní òkú. Ojú tí obìnrin fi wo ara rẹ̀ nínú eré *Ọ̀yọ̀* yìí kù díẹ̀ káàtó; kò yẹ kí obìnrin rí obìnrin ẹgbẹ́ rẹ̀ tó bí àkọ́bí ọmọ lókùú bí olórí burúkú àti ẹni tí a kò gbọ́dọ̀ jí kò láwùjọ. Bákan náà, a ṣe àkíyèsí pé àwọn tí wọ́n wá láti àwùjọ yìí tí wọ́n sì wà ní àyíká nìkan ni wọ́n lè gbọ́ èyíkéyìí nínú àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ inú eré *Ọ̀yọ̀* yìí ní àgbọ́yé;

nítorí náà, a dábàá pé kí á ṣe àmúlò ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé gẹ́gẹ́ bí àfikún sí àwọn ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àtijọ́ wọ̀nyí. Bí àpẹẹrẹ: a lè kọ ọ̀rọ̀ bí: ALÁKỌ̀Ọ́BÍ sára aṣọ tẹ́ẹ́rẹ́ tí ẹni tó ń ṣeré *Ọ̀yọ̀* lè wọ̀ bí irú èyí tí àwọn tí a fi àmì ẹ̀yẹ dá lọ́lá máa ń lò; èyí yóò lè mú kí ọ̀pọ̀ ènìyàn (àtonílé àtàlejò) mọ àrokò tí wọ́n ń fi ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àtijọ́ wọ̀nyí pa ránṣẹ́ sí àwùjọ náà; èyí yóò túbọ̀ fẹsẹ̀ ìgbọ́ra-ẹni-yé múlẹ̀ láwùjọ tí eré yìí ti ń wáyé.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Abímbọ́lá, W. (1977). *The Study of Yorùbá Literature.* An Inaugural Lecture of University of Ifẹ̀, Ilé-Ifẹ̀.

Adébọ̀wálé, O. (2005). "A Womanist Reading of *Rò Óo Re*". Nínú *Àmù:* Vol.1, o.i.32-55.

Adéoyè, C.L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Adéwọyè, Sam (1988). *The Essentials of Literature*. Ìbàdàn: Paperback Publishers.

Adéyẹmí, L. (2001). "Iṣẹ́ Ọ̀rọ̀ Láméyítọ́ Lítíréṣọ̀ Yorùbá". Nínú Àjàyí, B. (ed.) (2001) *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá, Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ Àti Àṣà.* Unilọrin: Department of Lingustics and Nigerian Languages. o.i. 145-166.

Àjàyí, B. (2017). The Role of the Yorùbá Talking Drum in Social Mobilisation, http://yorubaforacademicpurpose.blogspot.com.ng

Badà, S.O. (1973). *Òwe Yorùbá àti Ìṣẹ̀dálẹ̀ Wọn.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Bennet, T. (1979). *Formalism and Marxism*. Longon: Methuen.

Fáyẹmí, A.K. (2013). "Epistemological Virtues in Yorùbá Oral Media; Implications for Culture of Peace in Contemporary Africa". *The African Symposium: An online Journal of the*

*African Educational Research Network*. Vol. 13, No.1, June 2013 https://www.ncsu.edu/aern/TAS13.1/TAS13.1_Fayẹmi.pdf.

Kọ́láwọlé, M.E.M. (1997). *Womanism and African Consciousness.* Trenton: African World Press, Inc.

Ládélé, T.A.A., Mustapha, I. A., Aworìndé, O., Oyèrìndé, O. àti Ọládàpọ̀, O. (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá,* Ìbàdàn: Gavima Press Ltd.

Láyẹni, Ọláṣíji (1978). "Ètò Ogun Jíjà nílẹ̀ Yorùbá". Nínú Ọlájubù, O. (1978). *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá*, Ìbàdàn: Longman Nigeria Limited.

Mustapha, O., Oyèrìndé, O., Àlàgbé, A. àti Adébọ̀wálé, O. (2009). *Ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá Titun, Iwé Kẹ́ta.* Ìbàdàn: Ùniversity Press PLC.

Ọdẹ́tókun, A. Ògúnfọlájì, O., Adéṣígbìn, B., Olúnládé, T. àti Akinlabí, B. (2005). *Ìwé Ìgbáradì Fún Ìdánwò Yorùbá,* Lagos: Macmillan Nigeria Publishers Limited.

Ọlájubù, O. (1978). *Ìwé Àṣà Ìbílẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Longman Nigeria Limited.

Olútóyè, O. (1982). "Ọdún Obídan Ní Agbègbè Ọ̀wọ̀ Àti Àkókó" nínú *Olókun*, Ìwé Àtìgbàdégbà Ti Ẹgbẹ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá, Ìbàdàn: Longman Nig. Limited. No 13 o.i. 9-13.

Ọ̀pádọ̀tun, O. (1986). *Àrokò, Àwọn Àmì àti Ìró Ìbánisọ̀rọ̀ Ilẹ̀ Yorùbá Láyé Ìjelòó.* Ìbàdàn: Vantage Publishers.

Owólabí, O., Olunládé, T., Adéránti, B. àti Ọlábímtán, A. (1986). *Ìjìnlẹ̀ Èdè àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá, Ìwé Kejì.* Ìbàdàn: Evans Brothers (Nigeria Publishers) Limited.